**Akiyesi**

A nfẹ awọn ẹnia ti yio ma ba wa ta Irohin Imolẹ ni awọn ilu wọnyi Igbo-Ora Shaki Iseyin Erinwa Ilalaiẹ Akurẹ Ondo Ado-Ekiti Gbogan Fiditi Oyo Ede Ikorodu Shagamu Ilaro ati Ilora

E kowe si:-
Olotu IROHIN IMOLẸ
16, Bamgbose Street,
Lagos.

IROHIN IMOLẸ

MOTTO: IMOLẸ DE, OKUNKUN PARADA.

**To Let**

1 Room
With modern Amenities
Water System
24, Oliyide Street
Odu-Abore Mushin
Phone 21985

VOL. VI No. 334 MONDAY JUNE 25 —JULY 1 1962 KOBỌ MEJI (2)

## IWADI IWỌ ORUN KI YIO BGE ẸNIKẸNI

# Awọn ti a ti fi ofin pajawiri hamọ yio wa sọ tẹnu wọn

IBADAN:— A gbọ wipe ofin pajawiri ti Ijọba Alapapọse ṣe lori awọn ẹgbẹ Ọlọpẹ, ko mọ lori wọn nikan, o ti tun bẹ sori ẹgbẹ Alakukọ. Adajọ Coker sọ nile Igbimọ Iwadi wipe Iwadi yi, yio fẹ lati gbọ ọ r ọ lẹnu diẹ ninu awọn ti a fi ofin pajawiri mu, ẹnikẹni to ba si ni ifẹ lati wa sọrọ ninu Iwadi yi, ki o kọwe si Olori Oluwadi Ọgbẹni G. B. A. Coker.

Oluwadi agba sọ pe, kiṣe nitoripe a ti bura fun Ijọba lo mu wa lati fẹ ṣe Iwadi yi, ṣugbọn a ṣe e gẹgẹbi ẹtọ wa laigbe si ọtun tabi sosi, ati pẹlu ododo gẹgẹ bi ofin ti wi, ara ti ẹnikọkan wa bu jẹ otitọ wipe, a ko ni gbe ẹjọ alare fun ẹlẹbi.

Iwadi ti a fẹ ṣe yi, ko nṣe ti arufin gẹgẹbi eto ti wọn nṣe ninu Kotu awọn arufin. Bi o ti jẹ wipe ko nṣe ẹjọ arufin ni a fẹ ṣe yi, a fẹ ki o ye nyin wipe, ẹniti o ṣiketa ninu Iwadi yi. ko mọ owọ ko mọsẹ nipa ofin ko si nṣe Amofin rara, I w a d i yi ko nṣe ohun ti awọn Oṣelu yio ma wa se sunasi rara.

Iṣẹ tiwa ni pe, ki a ṣe I w a d i na toni-toni gẹgẹbi ẹsun awọn gbe ṣiwaju wa, lati fi ofin wadi ododo ọrọ na. Ẹnikẹni ti o ba gbe ẹmi I ṣ e l u wa ṣiwaju wa lati ma wa sọrọ ti ko ba oju mu, a o lo agbara wa lati le Oluwa rẹ jade, ati awọn ti o ba npurọ.

Nilu Eko ni a o fi ṣe ibujoko iwadi yi, ṣugbọn o le jẹ wipe a o tun gbe Ibujoko na lọ sibomiran, Oluwadi Agba wa kọju si awọn Oniwe Irohin, o ni, on ke si ẹnyin oniwe Irohin ki ẹ maṣe titori anfani ti ẹ ni wipe, ẹ le tẹ ohun kohun ti o ba wu nyin jade ki ẹ si fi ba nkan yi jẹ nitori nipa Iranlọwọ nyin ni a fi le ri ododo ọrọ na.

Ọgbẹni Fani Kayọde ni Oluwadi kọkọ pe lati wa sọ ti ẹnu rẹ, nwọn si ti gba aṣẹ lọdọ Dọkita Majẹkodunmi fun, on ni ẹniti yio kọkọ sọrọ nigbati Iwadi na ba bẹrẹ ni ọjọ 11th oṣu July 1962 Ọlọrun ko mu ọjọ ro.



Ẹniti a nwo ninu aworan yi ni adajọ Agba G. B. A. Coker, on ni a siwaju awọn adajọ mẹtẹta ti yio joko ṣe iwadi nipa bi Ijọba Iwọ-Orun ti ṣe nnawo Ijọba si. Orukọ awọn mẹtẹta na niwọnyi G. B. A. C o k e r, ni olori, awọn m e j i ti o ku ni Ọgbẹni J. O. Kassim ati Ọgbẹni Akintọla Williams.

Lọsẹ to mbọ, ẹ o ri aworan gbogbo awọn I g b i m ọ Iwadi na nigbati nwọn kọkọ bẹrẹ Iwadi na nilu Eko lọjọ A l a m i s i to kọja, ki nwọn to yọ si ọjọ kọkanla oṣu to mbọ (11th July 1962).

## Kinla! Ajao ku tabi Emini?

Bi ko ba si iru aye ti ẹgbẹ Ọlọpẹ wa loni ni, o yẹ ki gbogbo aiye mọ pe F. J. ṣalaisi. Ka irohin iku rẹ loju ewe Kẹjọ.

**STAR LAGER**

OFF-LICENCE SELLING PRICES
STAR large size bottle ... 2/9
STAR small size bottle ... 1/7

Selling price at Bars, Hotels and other on-licence premises
STAR large size bottle ... 3/-
STAR small size bottle ... 1/9

# ỌRỌ OLOTU

## ITIJU NI ỌNA YI JẸ

Ti titi kan ko ba dara ni arin Ilu, ki i ṣe onimoto, ı bi oni Basikulu nikan ni Ijọba nfi iya je. Eyiti ẹniti o nfi ẹsẹ rin ıjẹ lopo. Ti ẹnik ẹni ko ba si gba eyi ki o lọ si ọna Mushin ni ọjọ ti ojo ba rọ.

O ṣe ki o jẹ itiju fun Ijọba pe bi awọn ti o ngbe adugbo na ti o nsan owo ori to, awọn ko le tun ọna ti nwọn ngba lọ ṣiṣẹ ṣe fun wọn.

Alebu ọna yi pọ pupọ. Ko fẹ rara, koto ti omi nrọ si pọ larin rẹ ko si si ibudo ti o dara fun awọn moto ero. Gbogbo ẹnikẹni ti o ba si nkoja nibẹ yio ri alebu wọnyi.

Ṣugbọn ni iwọn igbati o jẹ wipe bi awọn Oṣelu pataki, ani awọn Olori ba fẹ jade, awọn oluṣeto ijade wọn ki i jẹ ki nwọn gba ibiti ko dara ninu ilu wa, ko le jẹ ki nwọn mọ eyiti o buru. Nisisiyi a ro pe awọn Oṣelu wọnyi yio ṣanu awọn ara Mushin ti o nsan owo ori lọdọdun lati tun ọna ṣe fun wọn.

## MUSHIN NIKAN KO

Ki i ṣe opopo ọna Agege si Mushin nikan ni ko ṣe ri. Pupọ ninu ọna Shomolu ni o buru gidi. Nitoto Ijọba ko le ri owo lẹkan lati ṣe gbogbo rẹ, ṣugbọn ewo ni Ijọba ni ọwọ si ninu titi Ṣomolu pe o dara.

Awa lodi si ki enia ma san owo ori, Iṣẹ gbogbo wa si ni owo sisan. Ṣugbọn bi o ba jẹ iṣẹ wa ni owo ori sisan o yẹ ki awọn Ijọba ma mọ pe iṣẹ a w ọ n ni lati ma lo owo ori wa fun Igbadun ati anfani wa.

## Ọmọ Ero Ilu Ọba kan ku iku ojiji

IBADAN:- Anu ṣeni lati gbọ wipe, ọmọ ile ẹkọ giga University kan ti ko ju ẹni ọdun-mẹdọgbọn lọ, ti oruko rẹ njẹ Samuel Nana, tio ti mura lati ba ọkọ ofurufu lọ si Oyinbo fun ilọsiwaju ẹkọ rẹ ni a gbọ pe o ku iku aburadi nigbati o nlọ dagbere fun awọn Obi rẹ. Ayọ lo sa npa enia a gbọ irohin pe bi o ti nwa moto onifaji kan lọ nigboro ilu Ibadan lojiji ọwọ rẹ ju, ti moto rẹ si sojudele sinu oju agbara kan. Ki awọn Onitalọwọ to de ibẹ lati fa a jade, agbako! o ti koja si ilẹ aiyeraiye.

## BỌLA ADEWUNMI DI LỌYA



Awọn ti a nwo ninu aworan yi ni awọn ọrẹ Ọgbẹni Bọla Adewunmi nigbati nwọn nṣe ayẹ ikini ku abọ fun on ati iyawo rẹ ti nwọn ṣẹṣẹ ti ilu Ọba de, nibiti nwọn gbe ti lọ ko iṣẹ Lọya.

Ki o to di wipe Ọgbẹni Adewunmi lọ si ilu Oyinbo, o ti kọkọ fi igba kan jẹ Igbakeji Olotu iwe Irohin kan nilu Eko.

Nibi ẹyẹ na: Ọgbẹni Adewunmi ni a nwo ninu aworan yi ti o wọ ewu dudu ni o duro si ẹgbẹ Ọgbẹni Sunday Shomuyiwa (Balẹ) ti ile iṣẹ United State Information ni ọwọ osi ti o wọ aṣọ funfun ati Ọgbẹni M. O. Awodeinde ti o nṣiṣẹ nile iṣẹ nla ti awọn oṣiṣẹ P & T ni o wa ni ọwọ ọtun.

# Yẹyẹnatu!

## O NI YẸYẸ EKO

Yẹyẹnatu:— Olotu, ẹ ku igbadun o. Ṣe a l a f i a ni Ajẹgborodagba ati Olofofo wa?

Olotu:— Alafia ni, a ti nreti rẹ kẹ.

Yẹyẹnatu:— Hẹ, ẹ ma b i n u o jare, Nwọn ni iṣẹ aje ko gbe iboji

Olotu:— Ibo lo wa ngbe?

Yẹyẹnatu:— Ilu ojo ati orun ni kẹ.

Olotu:— Iyẹn ma ga kẹ, i y ẹ n ni pe inu orun lo ti mbọ yi?

Yẹyẹnatu:— Ibi iṣẹ awọn Suberu ni Mo nlọ sibi iṣẹ l'Eko ko sa jẹ ka mọ ẹni ngbe igbẹ.

Olotu:— O ho, mi pe igbẹ ni Suberu ngbe nibi iṣẹ titun to ṣ ẹ ṣ ẹ nṣe?

Yẹyẹnatu:— Rara kẹ, Ṣugbọn haba o ya mi lẹnu pe, ohun ti ko le ṣe ninu ile rẹ lo nṣe nibẹ.

Olotu:— Kilo wa ṣe nbẹ ti ko le ṣe nile rẹ? Patapata a ma se onjẹ ti Iyawo nṣe fun nile nibẹ.



Yẹyẹnatu:— Bo tilẹ nṣe iyẹn, ko le ya mi lẹnu mọ, Ṣe Ọkọ temi na ro ẹba ta ri.
Ṣugbọn lẹhin igbati Suberu ti ba Iyawo rẹ ja pe on ko le —
Haba! Su-be-ru.

Olotu:— Kilo ṣe pa-a-pa?

Yẹyẹnatu:— Eni to ni obinrin ku mọ lo yẹ ko ma gbalẹ, a ṣe agbalẹ lo nṣe nibi iṣẹ. Eko ma ba jẹ o.
Gbogbo iṣẹ ti obinrin iba ma ṣe — ọkunrin ngbalẹ.

Olotu:- Kini iwọ wa lọ si Ọfisi wọn?

Yẹyẹnatu:— Iṣẹ ni kẹ.

Olotu:— Iwọ, iru iṣẹ wo lo wa fẹ ṣe?

Yẹyẹnatu:— Ho! ha! Akọwe ni kẹ. Ṣe ẹ mọ pe mi ti nlọ sile iwe alẹ?

Olotu:— Ṣe nwọn si ti gba rẹ?

Yẹyẹnatu:— Bi mi ṣe de bẹ - - ha emi funra mi - - ti mi lo ẹ w u

# IFẸ LOJU (APA II)

Nigbati Muli wọle Akin to ri ọrẹ ati Ọkọ rẹ, oju ti i, omi si bọ lo ju rẹ nitori pe o ti mọ nigbayi pe on ti huwa buruku s'Ọkọ on. Nwọn fun nijoko, o joko, Akin si bere ẹjọ lọwọ rẹ. Iya Bọlaji fi tanu-tanu dahun o ni ki nwọn ba on bẹ Ojogẹ, nitori on ko ni ohunkohun lati sọ. Ọrẹ rẹ si dahun o ni, Ṣe o ti gba pe ohun ti o ṣe ko dara ni? Akin si dahun o ni, Ẹ ma jẹ ka fa ọrọ yi gun, Oluwa Olodunmare ko ni jẹ ka ri ọrọn ẹbẹ larin gbogbo wa A m i n. Baba Bọlaji, ṣe o gbọ ohun ti Iyawo rẹ sọ? Oluwa Ọba to da n y i n pọ ko ma ni ya nyin o, Oluwa Ọba yio da ọmọ si fun nyin o, yio si ṣe ọkun ti anfani Amin.

Ẹ ma ranti Bọlaji o, Enyin mejeji ti Bọlaji ni kẹ ma wo o, ṣugbọn Iwọ Iya Bọlaji Agba dọwọ rẹ, o si yọ ka ba ọ sọrọ pupọ nitoripe pọu-ọn lo ṣe akoko idi tẹlẹtẹlẹ ki eleyi to sẹlẹ, emi ati ọrẹ rẹ ti gbero lati pe ọ, ki a ba ọ sọrọ. Ọkọ rẹ ti sọ ẹdun ọkan rẹ fun gbogbo wa. Iwọ papa mọ bi Ọkọ rẹ ṣe fẹran rẹ to, to ba lowo lọwọ lati ọjọ yi ni, o daju pe yio ti fun ọ, Họwu! Ṣe, bi o ba lowo lọwọ bi o ko tilẹ fun, o mọ pe Iwọ yio ma fun ọmọ on. O si ya emi l ẹ n u pupọ, iru iwa ti o tun wa nhu lẹnu ọjọ mẹta nwọnyi.

Nwọn ni Oṣika enia lo ngbọ ẹjọ ẹnikan da, (toto o) nitorina bi o ba ni ohun kan lati sọ jẹki a gbọ, Sikira ko si jẹ ki o sọrọ, ki o to fi itara dahun pe, Ẹ sa ba wa pari rẹ fun wọn, tabi kini o tun fẹ sọ Muli? Akin si dahun o ni, o ko le sọ bẹ r a r a, on na le ni ohun to fẹ sọ. Sikira ni, Mo mọ pe kiṣe ifẹ ọkan Iya Bọlaji ni gbogbo ohun to nsẹlẹ yi, Iya rẹ Agba lo ti ni itikuti Ni temi ṣa o, ẹnikan ko ma le ti mi pa o

Muli si dahun ni ikẹhin, o dupẹ pupọ lọwọ wọn, o si gba gbogbo ẹbi rẹ pẹlu ileri pe on yio yi pada si bi on ṣe nṣe ni ati ilẹ wa.

LATI ỌWỌ

Afolabi Olabimtan

Nwọn bere lọwọ O j o g ẹ bi o ba ti tan ninu rẹ, o si dahun o ni, Họwu! bi ko ba tan nkọ, kini ki nṣe, o kuku da mi loju pe, nigbati Iya ba de, nko ni ri oju Muli ni ilẹ mọ. Ju gbogbo rẹ lọ ṣa o ti tan ninu mi bi o tilẹ jẹ pe nko yi ti san gbese Ẹrọ akọrin mi tan.

Bayi ni awọn ọrẹ tọkọ-taya nwọn ṣe pari ija w ọ n onikaluku si gba ọna tirẹ lọ. O j o g ẹ pẹlu Aya rẹ tun ara wọn mu, apa ko jọ ibi ara mọ, ṣugbọn sibẹsibẹ ifẹ awọn mejeji ko dinku si ara wọn. Muli nfi ọwọ fun ọkọ rẹ ju ti akọkọ lọ, Ojogẹ si ngbiyanju lati gbagbe gbogbo ohun ti o ti sẹlẹ si ẹhin, Iya M u l i ko ṣe ọrẹ Ojogẹ mọ, bi bu ni o nbu kiri; ko si pada lẹhin Muli, iyẹn ko gbọ ẹkọ mọ nitori Ṣanko ti toju rẹ wọlẹ ko si jẹ tun bu Ọba Koso mọ.

Ọpọlọpọ ẹkọ ti Iya Muli nkọ si ọkọ rẹ ni ọmọ ngba ti ko si mu ṣẹ. Ni akọkọ, eyi ko han si Iya Muli nigbati o han si, inu bi pupọ, o si ro ni ọkan rẹ pe Ojogẹ fun Ọmọ on ni ogun jẹ, o pinnu lati ṣe egbogi ifẹran gbigbona fun Muli kio lo fun ọkọ rẹ.

---

# Akọwe kan ji owo iṣura ti Ijọba ni Akurẹ

AKURẸ:- Akọwe a gba owo kan (kaṣia) ti orukọ rẹ njẹ Stephen Agunsibo sọ niwaju Adajọ ni ile ẹjọ nla ti o wa ni Ado Ekiti wipe, Ọkunrin kan mu iwe owo wa si ọdọ on lati wa gba owo, on si san pọun mejidinlogotalelẹgbẹta fun. Ọgbẹni Agunsibọ jẹ Agbowoka (Cashier) fun ile iṣura (Treasury) ti Akurẹ on ni ẹlẹri fun awọn Ọlọpa nipa ẹsun ole ti nwọn fi sun Akọwe Ijọba kan ti o njẹ Alfred Osabiyi ti o ngba owo ti o fẹrẹ to apo mẹta lọdọdun ni abẹ Oyinbo onigbo to mbẹ ni Ẹkọ awọn Oyinbo Agbẹ labẹ Ijọba Iwọ orun ti Akurẹ.

# Ẹ KU OWURỌ O, ẸNYIN ỌMỌDE!

Mo ki gbogbo enyin Ọmọde, ẹ ku owurọ o. Ara o le bi. Gbogbo yin ni ẹ mọ pe asiko Ojo ni a wa nisisiyi, mo si ma ri ọpọlọpọ Ọmọde ti o ma nsare tabi ṣire ninu Ojo pelu ẹwu ojo nwọn, tabi lai ko wọ ẹwu Ojo, a si ma dun mọ nwọn ninu pupọ.

Awọn Olukọ yin ko si ni gba yin laye lati joko si aye yin ninu ile iwe bi aṣọ yin ba tutu.

Mo mọ daju wipe ko dara lati joko pelu ẹwu tutu ninu Ile Ẹkọ nitoripe o le fa otutu si yin l a r a otutu na si tun le fa aisan nimonia. (arun ti nmu enia lẹgbẹ).

Nitori eyi ẹ jọwọ enyin ọmọde ẹnyin ti ẹ ko ni ẹwu ojo ẹ sọ fun awọn Obi yin ki wọn tete ra ọkan fun yin pẹlu Bata Ojo. Alafia ara logun ọrọ.

Ilẹ Naijiria nfẹ ki awọn Olori Oṣelu Ilẹ wa lẹhin ọla wa ni Ilera ati Alafia, ki nwọn si ni agbara.

O digba kan na ẹnyin Ọmọde

Emi ni tiyin
LATIFU BABALOLA


BERE OJULOWO EGBOGI AWỌN FARANSE TI WỌN NPE NI:—

RICHALET

FUN ARUN EJẸ ARA ENIA GBOGBO




Eleyi yatọ patapata si awọn Rọbi-rọbi Iṣẹ re lara enia o si daju fun Iwosan gbogbo K o k o r o buburu ti o ba wa ninu "EJẸ ARA" bi Mọnọmọnọ.

Meji rẹ kosi ninu gbogbo awọn Egbogi ti wọn npe ni TỌNIKI Ejẹ ti wọn si nta kakiri ni owo pọọku, adimọwọ tabi ki o lọ nilẹ ko di owo. Iyẹn ṣe e w ọ awa ki ta awọn egbogi ba wọn yẹn rara tabi ti nwọn npota ni Ilẹ yi.

Gẹgẹbi awọn Onibara wa ti mọ irufẹ awọn gbogi ba wọnyẹn a ma ba ojulowo egbogi atata ti aranṣẹ fun tita lati awọn ilu Jamani, Faranse, ati ti a w ọ n Tatambulo si Itali jẹ mọ daju pe bi ẹjẹ ara ko ba mọ daradara awọn amodi tabi ailera wọnyi le ṣe ọ. Lakuregbe, orişirişi Inarun, Ojuṣuṣu tabi didun, Jẹdijẹdi Akọ-Iba, arun-Ẹdọki, Aya didun Tanpara ati Ekuru laya

Ara riro, Lapalapa, Egbo-Ẹsẹ Amodi Apo Ile ito, ẹhin didun tabi ibaradi riro pẹlu. Egbog Risalẹti a ma pa gbogbo kokori buruku ti o wa n i n u ẹjẹ aro patapata yio si fọ ẹjẹ rẹ mọ toniton pelu. Ṣa dan Igo rẹ kan wo lara rẹ dajudaju wọ yio ma rohin rẹ fun ẹlominran p ẹ l u nigbakugba.

Bere lọdọ awọn:-

**Waterloo Medicine Stores**
**8, Palmchurch Street Lagos,**
**Phone: 22878 Nigeria, (Oja ita Faji)**

ADEDUN CHEMIST
WAKEMAN STREET, YABA PHONE 22878

WATERLOO MEDICINE STORES
11, FAGBEWASA STREE. OSHOGBO

# *ẸGBẸ IMỌLẸ AIYE*

## Abọdẹrin ninu Igbo Mapẹran (Apa 8)

LATI OWỌ:— ABDULLAHI A. AWẸLẸNJẸ
No. 1 Ọmọ ẹgbẹ Imọlẹ Aiye

Ibi ti a ba Itan wa de, ni ibiti kiniun yi ti ri wa ti o si mbọ lọdọ wa. Bi o ti ku diẹ ko de ọdọ wa ni mo bọ siwaju ti mo kigbe lojiji wipe, Iwọ wo ni o mbọ? nibo lo ti mbọ? nibo lo nlọ? Ija lo ba wa tabi ọrẹ? sọrọ kia ki jamran to gbe ọ, nitori a ti gbọ pupọ nipa iwa ika rẹ si ọmọ enia, a si ti mura silẹ de Iku b'Iku ba de.

Bayi ni mo wi ti kiniun yi si da ọwọ rẹ delẹ to bu ramuramu, ohun na si wi fun wa bayi wipe, Emi ni kiniun Ibẹru, o jẹ kayefi nlanla fun mi pupọ lati ri wipe enia kan tun le wa ni aiye yi ti yio ri on ti jinnijinni ko ni bo Oluwarẹ, o wi siwaju si wipe, on ti wa ni orilẹ aiye yi, o le ni ẹgbẹwa ọdun ati pe enia ni on tẹlẹ, on si ni Onibode ile ọhun aṣọ Iku, nitori eyi on ti di ọrẹ pẹlu Iku, ati pe on ko le ku mọ, o si tun wi siwaju pe ohun to le on kuro ni Ọrun ni pe, on ba Iku wa si aiye lọjọ kan, on ri obinrin to dara kan on si fẹ ẹ, obinrin na si loyun, idi ni yi ti Ọlọrun fi kọ ti o si halaka on si ẹranko.

Bi o ti dakẹ ni a bi lere bi o ti ṣe raye fẹ obinrin na, o si wi pe ẹnikan ni awọn wa ṣe iṣẹ fun nibẹ, afẹri si ni awọn nrin, (ko si ẹniti o le ri nwọn). O ni bi awọn ti de ile na ni on ri obinrin na to sun bi o si ti jẹ wipe gbogbo enia ati obinrin na ko ri on, ni on ba tu aṣọ lara obinrin na, on si fẹ ẹ. O ni gẹrẹ ti on ṣe eyi Ọlọrun ti ri on, o si binu si on, ṣugbọn on ko le ku mọ. Nigbati o wi bayi tan Arikutaku bi lere pe Eṣe ti awọn ẹranko ati enia fi nsa fun ọ tobẹ ti okiki rẹ fi kan de gbogbo aiye? o si dahun pe nitori bi inu ba bi on, on le pa Erin ati pe gbogbo nkan ibẹru wa lara on.

Nigbati o wi bayi tan, o tun ki wa, o si ṣe wa lalejo bi ipa rẹ ti mọ, aṣe baba arugbo kan sapamọ o ngbọ gbogbo ohun ti a nwi, nikẹhin on na jade si wa, o si kiwa, o joko, nigbayi ni mo to wo ẹranko yi finnifinni. O ni ila li ọwọ, ọwọ rẹ ati awọn ẹsẹ ati oju rẹ si dabi ti enia gan ni.

Ni kẹhin a da gbere fun o si fun wa ni ẹbun kan bayi, O ni bi ija ba pọ ti a ko si ri ohun ti a le ṣe mọ, ki a bu ẹbu diẹ sọwọ wa, ki a si fẹ si ọna ile, O ni were a o ba ara wa nile wa.

Bayi ni a dagbere fun ẹranko yi ti a si tun ki Baba arugbo yi, a gba ọna igbo yi ti a mba irinkerindo wa lọ.

Lọsẹ to mbọ ni a de inu Igbo yi, ẹ tọju kọbọ meji nyin di ọsẹ to mbọ o. Ẹ ku ọdun o.

---

## Akiyesi Pataki

United Brethren Prayer Group.
'Egbe fe Enikeji re' gegebi ara re



Eyiti ọpọlọpọ enia mọ si "THE WHITE BROTHER HOOD LODGE" Njẹ iwọ ha mọ ohun ti agbara adura jẹ bi? Tabi o ha ti gbọ iṣẹ ribiribi ti Ẹgbẹ Oke yi nṣe fun ẹniti o ba aw ninu Idamu, t'owa ninu aiye bi eni pe ko si l'aiye.

Lọrọkan, kọwe si Akọwe Ẹgbẹ Oke yi fun iwe alaye pipe nipa Ẹgbẹ yi.

SECRETARY: Box 64, Yaba Nigeria.

---

## Kini o mọ nipa Ilẹ Naijiria?

1 Ọdun wo ni a yan Ogbẹni Jaja Wachuku gẹgẹbi Alaṣẹ Okere fun ilẹ Naijiria?
2 Ni gẹrẹ ti a gba Ominira tan tani tẹle Ọlọla Abubakar Tafawa Balewa lọ silu Amerika lati lọ mu ilẹ Naijiria wọ Ẹgbẹ gbogbo Igbimọ Agbaiye?
3 Tani Arabinrin na ti o jẹ Olumọran nipa ofin ati Igbakeji Alaṣẹ fun Ọga Agba fun ile Epo Mobil Oil ti ilẹ Naijiria?
4 Darukọ awọn Ọdọmọbinrin ti nwọn mu pe nwọn lẹwa ju ni ọdun 1960 ati 1961?
5 Nibo ni a bi Dọkita Lambo si? Lọdun wo ni a bi?
6 Darukọ Ile Ẹkọ-giga ti Arabinrin Jaiye-Ọla Adukọ Moor lọ?
7 Ilu wo ni Olu-ilu Iwọ-Orun Naijiria?
8 Ọdun wo ni Mungo Park ku?
9 Nibo hi Mungo Park ku si
10 Awọn Oyinbo wo ni o bẹ ilu Benin wo ninu ọdun 1472
Ọdun wo ni nwọn pin ilu Eko (Administration) patapata?
12 Ilu wo ni o kọ ko awọn Ologun wa ba Abẹokuta ni ọdun 1864?
13 Ọdun wo ni awọn Fulani ti c wa labẹ Usman Dan Fodio ṣẹgun Ilẹ-Hausa?
14 Lọdun 1841 si ọdun 1843, awọn Ijọ Ẹlẹsin Kiriyo bẹrẹ iṣẹ nilu Badagry ati Abẹokuta, Darukọ awọn Ẹlẹsin na?
15 Tani sọ pe:- gbogbo Eru ti o ba ti fi ẹsẹ kan ilu Oyinbo (London), O bori kuro loko Ẹru; lọdun wo ni o sọ bẹ?
16 Kini ohun meji pataki ti o ṣẹlẹ lọdun 1959?
17 Tani Alamojuto fun Ọkọ ofurufu ati ile Ifiweranṣẹ Ijọba Apapọ?
18 Tani Olori Amofin ati Alaṣẹ awọn Adajọ fun Ijọba Apapọ ilẹ Naijiria?
19 Tani Alamojuto owo fun Ijọba Iwọ-Orun tẹlẹ?
20 Akbejọro wo ni Ijọba Apapọ dapada pe ko gbọdọ duro ni Najiria.?

WO IDAHUN AWỌN IBERE WỌNYI LOJU EWE KEJE

---

## OWE ILẸ YORUBA

LATI ỌWỌ:- BILLIAMINU BALOGUN ALLI
No. 377 ỌMỌ ẸGBẸ IMỌLẸ AIYE

Ni igba lailai ti awọn agbalagba ba fẹ sọrọ kan wọn yio kọkọ pa owe, ṣugbọn nisisiyi mo fẹ lati ma ran yin leti diẹ ninu aṣa atijọ na. Emi yio pa owe diẹ fun yin gẹgẹbi ẹnyin na ti mọ pe owe ni ẹṣin ọrọ bi ọrọ ba sọnu owe ni a nfi wa. Diẹ ninu owe atijọ ni wọnyi:-

1 Ẹhin kule l'ọta wa, ile ni aseni ngbe.
2 A ngba Oromọ-adiẹ lọwọ Iku, o ni ki nwọn jẹki on re Atitan lọjọ.
3 Eri mọ aiye jẹ ki gun igi Ọpẹ
4 Ẹniti a npe ni ole ki gbe ọmọ ẹran jo.
5 Ẹni ba rin jinna a fi awo ibubẹ jẹun
6 Ẹni wa aiye ko pọ bi ẹni sin wọn wa
7 Gbẹnagbẹna gbẹ tan o ku Gbẹnugbẹnu
8 Imado iba ṣe bi Ẹlẹdẹ a ba ilu jẹ, Eru iba jọba enia iba ti ku kan
9 Ibi koju ibi bi a tiṣe bi ẹru bẹ ni a bi ọmọ
10 Aisi nile ologbo ile di ile Ekute
11 Bi igbin nre ajo a fi ile rẹ ṣe ẹru
12 Ironu ikoko ni'pa Aja
13 Gbogbo Alamu lo da inu delẹ a ko mọ eyiti inu nrun
14 Ohun ti agbalagba nfi njẹ Ẹkọ abẹ owe lo wa

# OFIN

Lati ọwọ:- WOLI KOGBEREGBE

Iwọ ko gbọdọ pania, Iwọ kc gbọdọ jẹri eke. Iwọ ko gbọdọ sọrọ Ọmọ ẹnikeji rẹ lẹhin, Iwọ ko gbọdọ ṣe ofofo nitoripe ete werewere ni Ọlọrun yio fi jona, gbogbo ẹnyin Obinrin Ilu eko, gbọ ofin yi o, Iwọ ko gbọdọ jowun, Iwọ ko gbọdọ fi isasun rẹ se isekuse isasun to ba se isekuse ni Oluwa yio fọ sori ina, Ha! Ha! yio si ṣẹ ara adugbo oju yio si ti obinrin to nse ọbẹ na, mo fẹ ki ẹ mọ wipe ohunkohun ti olukuluku ba gbin ni yio ka, ẹ lọ ṣe rere nitoripe ẹni ba fi ibi san ore ibi ko ni tan nilẹ rẹ lai lai Iwọ ko gbọdọ fi aṣọ alaṣọ bọ ara rẹ nitoripe aṣọ jagba-jagba ni Oluwa yio faya mo fẹ ki ẹ mọ wipe Oluwa ko rira awọn onisẹ ẹsẹ, Inu Oluwa ko si ni dun si awọn oloju kokoro, Ha! gbogbo ẹnyin kẹsimani Ilu eko ati iwọ Manija oloju kokoro, to fẹ gbe ile aiye mi i, tani olowo to le da ile aiye yi gbe.

Ẹlẹṣẹ kan ko ni lọ laijiya, ki ẹniti o nje maṣe kẹgan ẹniti ko ri jẹ, ki ẹniit ko jẹ maṣe da ẹniti o njẹ lẹjọ ROMU, 14, ẸSẸ 3.



Mo sọ fun gbogbo yin wipe ohun rere ko yẹ ẹniti o kotira alafia bẹ si ni ohun rere ko yẹ aṣiwere, Ha! ẹ wo o gbogbo ẹnyin ọlọrọ ẹ ma sọkun ki ẹ si ma pohun rare ẹkun nitori osi yi mbọ wa ta yin JAKỌBU 5 ẸSẸ 1 Ha! ẹnu ya mi nigbati mo de jlu, olofofo, abanijẹ ati apania ti pọju ni ile, ẹ ro ọrọ na wo ko si ninu olowo kan to le ku ki nwọn fi mọto ṣe posi rẹ. baba Onile kan ko le ru biriki lọ si ọrun lọ kọ ile, ka ma ri. Iwọ ko wa ile aiye mọya, ẹnikẹni ti o ba wa ile aiye mọya yio gunlẹ si ebute ofo, ọdaju enia pọju nilu eko titi lọ de muṣhin, wọn gbe mi ni kẹkẹ lọ ni muṣhin wọn si gbe mi ni bata ni itirẹ.

o ya mi lẹnu pupọ, iwa buburu ko yẹ ọmọ enia, kuro ni ibi ki o si ma ṣe rere ki o si ma joko lailai ninu rere ṣi ṣe, nitori ti Oluwa fẹ idajọ ko si kọ awọn enia rẹ silẹ, a si pa wọn mọ titi lailai, ṣugbọn iru ọmọ enia buburu ni a o ge kuro, olododo ni yio jogun aiye, yio si ma gbe inu rẹ titi lailai.

Ẹnu olododo ni o ma sọrọ ọgbọn, ahọn rẹ a si ma sọrọ idajọ, Ofin Ọlọrun mbẹ ni aiya rẹ, ọkan ninu irin rẹ ki yio yẹ, Ẹni buburu nṣọ olododo, o si nwa ọna lati pa a ORIN DAFIDI 37, ẸSẸ 27.

Ete werewere ni Oluwa yio fi jona, bi ọmọ ba ti ẹ jale a gbe ohun to yẹ, ohun rere ko ni kọja ọmọ Ọlọrun boni wahala ki o kọja enia buburu, aṣoju ni baba ọṣẹ Ibunkun ni fun ẹniti o ba fi ti Oluwa ṣe igbẹkẹle, Olotu wa ati Ajẹgborodagba ati gbogbo ẹnyin ti ẹ wa ni idi Iwe Irohin Imọlẹ Oluwa yio fun gbogbo wa ni alafia lati ma fi ṣe iṣẹ na, Amin.

---

# Awọn Alejo meji kan de silẹ Naijiria lati ilu Oyinbo

## BALEWA YAN AWỌN OLUWADI

EKO:- Awọn Oguna gbongbo meji kan to mọ pupọ nipa bi a ti ṣe nna owo ninu ewo siṣe ti de silu Eko, awọn si ti bẹrẹ iṣẹ wọn, Alhaji Tafawa Balewa ni a gbọ pe o ranṣẹ pe awọn Ogbologbo mejeji na wa lati Ilu Oyinbo wa fun Iwadi Ijọba Iwọ Orun.

Awọn enia mẹta ni a gbọ pe yio joko papọ ṣe iwadi ọrọ na ati wipe Adajọ Agba Ọgbẹni G. B. A. Coker ni yio ṣe alaga awọn Oluwadi ọrọ na. Awọn enia meji ti yio jẹ iṣọngbe rẹ lọtun ati losi ni Adajọ agba James Kasumu ati Akintola Williams, enia dudu ti o mọ pupọ nipa bi awọn onisowo ti ṣe nna owo si atiṣbi nwọn ti nfi owo pamọ si.



Ọlọla Alhaji Abubakar Tafawa Balewa

Ẹniti yio jẹ Akọwe fun iwadi na ni Ọlatunde Tanimọwo. Awọn nwọnyi ni nwọn ma ṣe iwadi nipa ọrọ wọn:- Marketing Board, Development Corporation, Finance Corporation; Housing Corporation, Broadcasting Corporation ati Printing Corporation. Lori awọn ibiṣowo mẹfẹfa wọnyi ni nwọn ma ṣe Iwadi le lori.

IWADI NA TI BẸRẸ LATI ỌJỌ ALAMISI

Gẹgẹbi irohin ti a gbọ, [illegible] ti bẹrẹ lati ọjọ Alamisi to kọja yi. Gbogbo [illegible] ilẹ ti o ṣe ti Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun ni nwọn yio ṣe iwadi rẹ.

AJẸGBORODAGBA NKI YIN O!

# Ha! Ọmọde-binrin meji wọ ijakadi nitori Ọmọ ọdun-mejila

NWỌN JA TITI NWỌN TU ARA WỌN SI IHORIHO

Ari male panu mọ, ni emi Ajẹgborodagba, agbọ ma le mu ọkan kuro ni emi Ọkọ Adiyatu, ẹniti o ba nrin irinkurin ni ohun gbogbo ma nṣe oju rẹ ohun lo difa fun mi lọjọ Alaruba ninu ọsẹ to koja nigbati mo gbera lati lati lọ wo ọrẹ mi kan ni Agbolle Saba ni opopo Shitta ni Eko.

Bi mo ti nlọ ni ọna Ọluwọle ti mo si sọda Titi Martin ni mo ba ya si ọna Shitta St., bi mo ti de ibi idi-odo Ijọba gan ni mo ri awọn Ọmọdebinrin meji ti nwọn wọ iya ija ti awọn Ero si pagbo fun nwọn, gbogbo awọn ọdọ-mọkurin ti o wa nibẹ nṣe ni nwọn nho ye le wọn lori, laiko la awọn mejeji yi, mo wa bere lọwo Ọgbẹni kan ti o wa nibẹ pe kini de ti ẹ ko fi la wọn? O ni awọn ti la wọn titi nwọn ko gbọ. Ọmọdebinrin k a r ti o jẹ Ọ r ẹ ọkan ninu a w ọ n Ọmọdebinrin ti o nja yi sọ fun mi pe lati Onikan ni nwọn ti nja bọ. ki nwọn to de ibin.

Nigbati mo gbọ b a ṣ i, mo kigbe mọ wọn lo jiji, aya awọn mejeji si ja. nitori ede Oyinbo ni mo fi sọrọ na. Nwọn duro nitori nwọn lerope Ọlopa ni mi ṣugbọn ihoriho ni a w ọ n mejeji wa nitori gbogbo aṣọ ọrun ara wọn ni nwọn ti fa ya wẹlẹ wẹlẹ.

Ọrẹ korikosun si ni awọn ọmọdebinrin mejeji ti o nja nitori ọkunrin yi o.

Mo bere ohun ti o fa ija lọwọ awọn mejeji. nwọn si ro ẹjọ pe nitori Fatayi ni laiko ti ju rara Ikini ni emi ni mo kọkọ nfẹ Fatayi ki iwọ to nfẹ, ekeji ni on ni eleyi lo da ija silẹ l a t i n awọn mejeji ti nwọn fi ja titi ti nwọn fi tu a r a wọn si ihoriho ẹnikan sọ fun mi pe ọmọ ti nwọn nja nitori rẹ yi, ọmọ ile iwe ni, ko si ju ọmọ ọ d u n mejila lọ, bakana ni awọn ọmọdebinrin mejeji wọn ko ju ọmọ ọdun m ẹ w a si mọkọnla lọ.

### O YẸ KI Ẹ RO ORI YIN WO ẸNYIN ỌMỌDEBINRIN

Ha! iwọ ọmọdebinrin ti o ti iwoyi lọ gbe igba ọkọ fifẹ dani o jẹ lọ ro ori rẹ wo o tọ o si ye pe ki o ro ori rẹ wo, ẹ nti i w o y i ja nitori ọkunrin, nigbati koti fẹ yin dele, ile ẹkọ ni awọn Oba yin ran y i n lọ, nwọn npa ebi mọnu ran yin lọ si ile ẹkọ, nitori ki ẹ ba le di ẹni ala lẹhin ọla ṣ u g b ọ n Ọkunrin ni O l o r i buruku yin nko si ọkọn ti ẹ si nlu ara yin nitori rẹ. Ọkuurin ko ja nitori yin mọ, ẹnyin ni ẹtun nja nitori ọkunrin ẹ jẹki ori yin fa epo. bi nwọn ba ni fun yin l o y u n tan, nwọn yio fi ẹsẹ fẹ, pe awọn ko mọ yin ri.

## YE IRAWO RE WO

Yẹ irawọ rẹ wo, kio si mọ kini ohun ti yio hu jade fun ọ ninu ọsẹ yi. Nitori ogun agbọ tẹlẹ ko npa Arọ.

Jan 20-Feb 18 (Aquarius) Arafyio rọ ọ wẹsi larin ọsẹ yi gbogbo ohun ti o tun jẹ iṣoro fun ọ. ni iwọ yio yanju kedere, Iwọ yio si ba obinrin lopọ ninu ọsẹ yi.

Feb 19-Mar 20 (Pisces) Oju Ọrun yio daru ni akoko owurọ, ṣugbọn yio mọ kuda a nigba aṣalẹ. Ọsẹ yi yio dara fun ọ lati fẹ Iyawo ati lati lọ ṣe abẹwo.

Mar 21-Apl 19 (Aries) Ilera yio wa fun ọ ninu ọsẹ yi nkan yio si ma lo dede fun ọ ninu ọsẹ yi, ṣugbọn nkan yio diju fun ọ nigba ọjọrọ.

Apl 20-May 20 (Taurus) Igba yio dara fun ọ lọsẹ yi iwọ yio lowo lọwọ fun igba diẹ.

May 21-June 20 (Gemini) Ṣe suru pupọ ninu ọsẹ yi nitori pe gbogbo awọn enia to yi ọ ka, ni yio ma kanra mọ ọ Iwọ yio si ri rire pubọ jẹ lori oja tabi lori nkan miran

June 21-July 20 (Cancer) Iwọ yio ba orire pade lọsẹ yi nibi gbogbo ṣugbọn arẹ yio mu ọ ni aṣalẹ

July 21-Aug 22 (Leo) Mora lati jẹ anfani ire ti o ti de si ọ kio ba le gbọṣẹ kan siwaju, sọra kio ma ṣe fi asiri rẹ han ẹnikan.

Aug 23-Spt 22 (Virgo) Gbogbo irawọ rẹ ni yio t a n ninu ọsẹ yi, fi ọdọ obinrin ni kio ma ṣe sunmọ kio ma ba ba ala orire rẹ jẹ

Sept 23 - Oct 22 (Libra) Maṣe simi pupọ ju bẹni ki o maṣe ṣe abẹwo enia pupọ nitori alafia ara rẹ ọsẹ yi dara fun ọ lati kọ iwe si enia.

Oct 23 - Nov 21 (Scorpio) Toju ọrọ aṣiri ara rẹ, ki o si gbidanwo lati simi di ẹ iṣọ rẹ yio dara jọjọ ni ọsẹ iwọ yio si ri ojure gbajumọ kan

Nov 22 - Dec 21 (Sagittarius) Ọrọ kan ti o ti fun ọ ni iyọnu kan yio dide si ọ ma fi ṣe Ibinu uṣe ni ki o wa ọrẹ kun ọrẹ.

Dec 22 - Jan 19 (Capricorn) Gba iṣimi lẹnu lẹẹ ki o si lọ sun di ọ maṣe ba ẹnikan weregbe ọ w ọ rẹ yio di pupọ ni ibi lẹẹ.

GBANGBA DEKUN!! KEDERE BẸWO!!!




PORAL

OLUBORI EGBOGI "IKỌ"

Bi amodi "IKỌ" ti ọjọ rẹ ti pẹ tabi ti o nyọ ọ lẹnu fun nkan bi ọdun kan tabi jubẹ lọ awọn egbogi rọbi rọbi ko le ṣe iwosan rẹ rara. ma fi owo rẹ ṣe ofo mọ.

Bere fun egbogi awọn ara Ilu Faranse ti nwọn npe ni "PORAL" Ojulowo haun haun, atamatọse egbogi fun Ikọ Fere, Ikọ tutu, Ikọ ọna ọfun, Ikọ igba aiya, Ikọ lile Ikọ" ti o ma mu enia lu kẹlọbẹ nigbakugba lati inu Ifun wa (Lungs) tabi ti o ma nmu enia ru pẹlu. Bi o ba dan Igo kan egbogi PORAL wo. Iwọ na yio ri iyatọ l a r a rẹ ni kiakia Igba aiya tabi ọna ọfun rẹ ti o ma nho yio duro "IKỌ" rẹ yio si san patapata, iwọ yio ma jẹun daradara Iwọ yio si ma sun fọnfọn pẹlu alafia ara.

Bere egbogi yi ati awọn oriṣiriṣi egbogi Ikọ m i r a n ni Ṣọbu awọn.

**Waterloo Medicine Stores**
**8, Palmchurch Street, Lagos, Nigeria.**
**Phone: 22878 (Oja ita Faji)**

ADEDUN CHEMIST
WAKEMAN STREET, YABA PHONE: 22878

WATERLOO MEDICINE STORES
11A, FAGBEWESA STREET, OSHOGBO.

ATI NI ṢỌBU IBADAN:-
IṢẸ OLODUMARE DISPENSARY OKE BỌLA

# IWI ASIKO

LATI ỌWỌ:- Afolabi Ojelabi

# BAIYE BA JA

Mo ki gbogbo ẹni tanṣẹ pe ki nfiyedenu o
Mo ki gbogbo Imulẹ to ni nfọkan balẹ
Mo ki nyin ọ ku ifẹ mi
Emi Atanda-ọlo baba Olufọlabi
Nwọn ni ki nma sọra bi mba nkewi mi
Nwọn ni nitoripe, aiye fẹlẹ o ti di dẹlẹnkẹdẹ
Nwọn ni ẹni ba ṣo nilẹ yi
Nwọn a lo ṣo pọba ni
Eni tutọ yi, nwọn a lo pọba
Gbogbo ẹni ba lulu nilẹyi o
Nwọn a lo bu Ọba
Mo ni ayọkẹlẹ ni wọle oloyin loruko iku
Aringbẹṣẹ wọja ayọ loruko arun
Mo ni ori ki i fawun, ẹdọ ki i dun igbin
Mo ni mo mọ oruko iku ki lo ma fi mi ṣe
Mo mọ Tarun ki lo ma fi mi ṣe

ORIN:- Ntori ori i fawun
Edọ ki i dun gbin
Otutu ki mmja lalẹ odo
Ibi wọn ri o. ki nwọn kigbe mi lọ

Arinitan-ṣẹ-ni nibi loruko Ọta ile o
Afinihan falẹkun sọna loruko ọta ọdẹdẹ
Aṣenitan fi ẹkun soju lọta Obinrin
Atori-owo yọ tanna iyẹn nti oṣelu
Atori ogun yọ apo iyẹn ni tọmọ Iya ẹni
Bi baba ba nile, ọjọ o ba ku Lọmọ Iya dọta
Bi baba loko, ọjọ toba ku Lọmọ Iya taka sira
Baiye ba ja ọmọ Ade
Baiye ba ja ko ṣe ṣo
Bọta ile ba faiye bi ko ja o ka orire
Bọta ọdẹdẹ faiye bi ko ja o ku orire
Bobinrin faiye bi ko ja o ku orire
Bika faiye bi ko ja o ku orire
Ntori baiye ba ja, baiye ba ja ko ma ṣe ṣo
Bo olejo, bo ko dẹhin jagun a dide duro
Bọmọ ba sun kan ogiri a yida dandan
Ọmọ Ade, A ki foro inu ṣọkọ iyalode
A ki i fi iwa ika loye nigbalẹ
Ntori igbẹhin o

ORIN:- Igbẹhin lọran
Bo ndun loni
Igbẹhin lọran

Baiye ba ja, ọmọ Ade ko ma ṣe ṣo o
E ma fẹṣọ jaiye
Ntori aiye fọlẹ o ja akikara lọ

## Oloye J.A. Ajao di Ologbe

EKO:- Sa wo o bi awọn alagbara ti nṣubu ti ohun ija si nṣegbe, anu ṣe ni jọjọ lati gbọ irohin iku Oloye J. A. AJAO, ti iṣe Ọtun Ọyọ ati Balogun fun ile Awọ. A gbọ wipe o bi ọmọ pupọ ati wipe ọkan ninu awọn ọmọ rẹ lo fẹ Alayeluwa Deji Ọba Akurẹ on si ni ijoye Eiyẹṣọrun ninu awọn iyawo Ọba (Iyale iyawo Ọba)

Lakoko ti F. J. (Ajao ni nwọn npe bẹ) fi ku ọmọ rẹ ti ṣe Iyawo Ọba ilu Akurẹ ko si nile, o ba ọba gbatẹgun alafia lọ silu Oyinbo, nitorina nigbati o ku nwọn ko le sinku rẹ lẹhin ọmọ rẹ, nwọn si sure tẹ waya si i nilu Oyinbo. Ni ọjọ keji ni iyawo Ọba ati Ọba gunlẹ si Eko, nwọn si ti bẹ rẹ si ṣe eto.

Ni Satide Ijẹta ni nwọn sinku rẹ nwọn si ṣe Isin Ikẹhin fun ninu ile isin Onitẹbọmi eyi ni ile isin ti ijọ Baptist ni Eko.

## Ikede Pataki

Fun awọn Onibara wa ti nwọn fi owo silẹ fun awọn iwe wa ti o tan laipẹ yi. Inu wa dun lati sọ fun wọn pe a ti ni wọn lọwọ nisisiyi.

Awọn ni:— IWE ASIRI ỌBA SOLOMON 20/- IWE AṢIRI ỌBA DAFIDI 20/-, IWE KẸFA-KEJE KEJỌ ati KESAN MOSE 20/-, LILO ati AGBARA PSALM 5/6d, IWE ALA 5/6d IWE ADURA PELU ORUKỌ MIMỌ JEHOFA 5/6d, IWE ADURA AṢIRI FUN AWỌN ẸGBẸ ALADURA BI IJỌ KERUBU ati SERAFU 5/6d, IWE IWOSAN AWỌN ADAHUNSE 2/-, IWE ILANA POOL LEDE YORUBA 2/- ati ogunlọgọ ohun miran

Kọwe si Manager, 232, Herbert Macaulay Street, Yaba, Nigeria.

## O ku Ọjọ marun loni!

Lẹkansi ani lati tun ran gbogbo ẹnyin ọmọ Ẹgbẹ Imọlẹ niye ti agbegbe Eko leti pe ariyanjiyan ti a fẹ ṣe ku ọjọ marun loni. (Ọjọ Satide to mbọ yi ni o.)

Gẹgẹbi gbogbo yin ti mọ ọrọ ti a o ṣe ariyanjiyan lori rẹ, eyi ni "IṢẸ AGBẸ ATI IṢẸ DỌKITA"

Eyi ni orukọ awọn ti yio nibi sọrọ ariyanjiyan na ati ohun ti ẹnikankan yio sọrọ le lori.

| IṢẸ AGBẸ | IṢẸ DỌKITA |
|---|---|
| 1, Muritala Azeez. | 1, Abudulai Awelẹnje. |
| 2 Whaeed Owokoniran. | 2, Fatai Oyerọgba. |
| 3 Olaiwọla Akande. | 3, Amuda A. Adeyẹmi. |
| 4, Babatunde B. Salami. | 4, Kamọru Abbase. |
| 5, Sule Cole. | 5, Sumọnu Alabi. |
| 6, Adelani Saibu, tabi Rasheed Esunaike Adagbafura. | 6, Kọlawọle Idosu |

Jọwọ iwọ ti o ba ri orukọ rẹ nihin maṣe jẹki o pẹ ki o to de ni ọjọ na. O yẹ ki o ti de ibẹ ki agogo mẹta abọ to lu. No. 9, Bamgboṣe Street Lagos ni a ti ṣe.

LATIFU BABALỌLA.
Akọwe Agba

ỌGBẸNI AFỌLABI ỌLABINTAN
Ni yio jẹ Alaga.

## Akiyesi Pataki


### Sengovan Tablets! Sengovan Tablets!!

SENGOVAN TABLETS:- Jẹ Ajidewe egbogi fun awọn agbalagba ati Ileta gẹgẹbi Ọmọkunrin.

SENGOVAN:- jẹ ọkan pataki ti a ṣe iwadi ni Ilu Okere ni Ilẹ Jamani lọwọ ọkan ninu awọn Ọjọgbọn Oniṣegun Arẹmọ ti Ilu Western Jarmani fun ara ara eyiti ọjọ ori rẹ to Ogoji si Ọgọrin ọdun (40-80 years).

SENGOVAN jẹ egbogi ti o ti wa lọjọ pipẹ fun anfani awọn agbalagba ilu Jarmani ki a to ṣe amuwa rẹ si Ilu Naijiria Ajẹbidan ni ogun yi Irohin ko to afoju ba.

Bere: A o ri lọwọ awọn Oniṣegun (Doctor) Naijiria tabi lọwọ alagba Messers HASSAN COMMERCIAL MEDICINE STORE 26, BISHOP STREET LAGOS PHONE: 28756. DIRECTION: 1 to 2 pills sufficient for your constitution, if so do not take more pills at one times SENGOVAN IS FOR YOU.

### Ibanuje tabi Ironu re de Opin Ayo de!

BERE EGBOGI AWỌN FARANSE TI WỌN NPE:—

**"CORSIVERA"**

Ojulowo ati Ajẹbidan Atamatase Egbogi ti a ṣe ni pataki fun:

"ARỌNKINIṢA TABI ARỌN LATỌNLATỌN"

MEJI RẸ KOSI.

Bere lọdọ awọn:—

**Waterloo Medicine Stores**
**8, Palmchurch Street, Lagos, Nigeria.**
**Phone: 22878 (Oja ita Faji)**


*Printed and Published by MODUPẸ PRINTING PRESS 16, Bamgbose Street, P. O. Box 1495, Phone 21985, Lagos. Olotu E. A. Adeniji 24, Olliyide Street, Odu Abẹrẹ Mushin.*